# ORI OKE INA ATI IṢẸ IYANU

Olu Ile Iṣẹ Iranṣẹ, Ipinlẹ Eko, Nijeria.

ETO IPADE AGBARA GBỌDỌ PARỌ ỌWỌ

## FI IYẸ GOKE BI IDI (APA KEJI)

**OṢU KEJE, ỌDUN 2019**

**Bibeli Kika:** I Sam.17

**Ijẹwọ:** Isaiah 40:31

## ORIN IYIN ATI IJỌSIN TI O L'AGBARA

1. Ọlọrun dide, Ki O si faatu, ohunkohun ti O ko gbin sinu Ijọ Ori Oke Ina ati Iṣẹ Iyanu, ni orukọ Jesu.
2. Ọlọrun, jẹ ki Ina isọji ba le Ori Oke Ina ati Iṣẹ Iyanu, ni orukọ Jesu.
3. Ọlọrun, jẹ ki agbara alafia ati itẹsiwaju ṣiji bo orilẹ-ede yi, ni orukọ Jesu.
4. Ọlọrun dide, ki O si fun wa ni awọn adari ti o ni ibẹru Rẹ, ni orukọ Jesu.
5. Jesu, ọmọ Dafidi, ṣaanu fun mi loni.
6. Ọwọ buburu iyowu ti wọn gbe le mi lori, gbana, ni orukọ Jesu.
7. Alaja ti nko reti, ti ko ṣẹlẹ ni iran mi ri, farahan ninu aye mi, ni orukọ Jesu.
8. Oluwa, fi igbedide mi da awọn ọta mi lohun, ni orukọ Jesu.
9. Ọlọrun Ori oke yi, jẹ ki nba ojiṣẹ Rẹ pade ninu ipade oṣu yi, ni orukọ Jesu.
10. Ọlọrun dide, jẹ ki ngbọ Ohun Rẹ, jẹ ki ibanujẹ mi d'opin, ni orukọ Jesu.
11. Agbara ti ndena ifọkanbalẹ, wọnu ide, ni orukọ Jesu.
12. Irawọ mi, ogo mi, kọ lati dakẹ jẹ; fọhun jade, ni orukọ Jesu.
13. Awọn nkan ti yoo ṣe irawọ mi ni anfani, ti ọta ti ji lọ, mo gba ọ pada, ni orukọ Jesu.
14. Iwọ òrùn buburu ti mbo irawọ mi mọlẹ, poora, ni orukọ Jesu.
15. Agbara ti o gba awọn ẹtọ mi mu ṣinṣin, jọwọ wọn, ni orukọ Jesu.
16. Gbogbo agbara ti ngan ọjọ ọla mi, gba itiju, ni orukọ Jesu.
17. Ọlọrun dide ki O si gba ayanmọ mi kuro lọwọ irakoro, ni orukọ Jesu.
18. Aye mi ati ayanmọ mi, jade kuro ninu igi buburu iyowu, ni orukọ Jesu.
19. Mo kọ lati di irawọ alarinka, ni orukọ Jesu.
20. Awọn ijoye ti wọn to silẹ lodi si angẹli iranwọ mi, ẹ tẹriba, ni orukọ Jesu.
21. Agbara ti wọn yan lati mu mi jiya nitori aiṣedede awọn obi mi, ku, ni orukọ Jesu.
22. Gbogbo igbekun ti mo jogunba latari aṣiṣe awọn obi mi, fọ, ni orukọ Jesu.
23. Ọlọrun dide, ki O si gba mi lọwọ awọn egun aimọ, ni orukọ Jesu.
24. Agbara ti njo ire mu kuro ni agọ ara mi, mo pa ọ run loni, ni orukọ Jesu.
25. Ọwọ alagbara buburu ti nni aye mi lara, gbana, ni orukọ Jesu.
26. Agbara buburu iyowu ti ngbawẹ ibi lodi si mi, ku lojiji, ni orukọ Jesu.
27. Gbogbo kọkọrọ alumọni rere ti wọn gba lọ lọwọ mi, mo gba a pada, ni orukọ Jesu.
28. Ọlọrun dide, ki O si fi titobi Rẹ han ninu aye mi, ni orukọ Jesu.
29. Ọlọrun dide ki O si jẹ ki nniriri bi O ti tobi to l'oṣu yi, ni orukọ Jesu.
30. Mo gba oju atokewa lati ri ogo mi, ni orukọ Jesu.
31. Irugbin iyowu ti wọn yan lati pa aye mi run, ku, ni orukọ Jesu.
32. Ọlọrun dide, ki O si ran olugbeni s'oke si mi, ni orukọ Jesu.
33. Ọwọ nla Ọlọrun ti ngba ni lọwọ ogun, dide, ja fun mi, ni orukọ Jesu.
34. Ogun iyowu ti o ti de mi mọlẹ, ki nto kuro lori oke yi, ja, ni orukọ Jesu.
35. Ire ati itẹsiwaju ti ko ṣẹlẹ ni ile baba mi ri, ba le aye mi, ni orukọ Jesu.
36. Ohunkohun ti o duro bii Golayati ninu aye mi, ṣubu, ki o ma si ṣe dide mọ, ni orukọ Jesu.
37. Ina itusilẹ, bu ramuramu, wọnu ipilẹ mi lọ, ni orukọ Jesu.
38. Ohun aṣeti, ti nfọhun lodi si mi, mo ba ọwi, ni orukọ Jesu.
39. Ororo buburu lati ile baba mi ti mbẹ lori mi, gbẹ danu, ni orukọ Jesu.
40. Ọwọ Hẹrọdu lori aye mi, mo dana sun ọ, ni orukọ Jesu.